# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KẸ́WA, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**ÀDÚRÀ SÓRÍ OHUN-ÈLÒ IṢẸ́ (3)**

## OṢÙ KẸ́WÀ 2023 - ÀDÚRÀ SÓRÍ OHUN-ÈLÒ IṢẸ́ (3)

## AWỌN ORIN IBẸẸRẸ

1. **Gbé Olúwa ga pẹ̀lú mi,**

Ẹ̀yin ènìyàn Rẹ,
Kí gbogbo ẹ̀dá alàyè,
Ma yọ̀ l'órúkọ Rẹ̀,
Fún ìfẹ́ tí Ó n fihàn,
Fún ìsinmi l'ọ́kàn wa,
Fún igbàlà kíkún Rẹ̀,
Tìrẹ lọpẹ́.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa tìtí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa tìtí láíláí,
Àní, títí láíláí,

2. Ẹ̀yin fún ìwà-mímọ́ Rẹ,

Fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ,
Kọrin ìyìn fún ẹ̀jẹ̀ Rẹ,
Tó fi rà wá padà,
Ìfẹ́ ló fi wá wa rí,
Nínú ìrà ẹ̀sẹ̀ wa,

Ó f’ọ̀nà ìyè hàn wá,
Ẹ f’ọpẹ́ fun.

3. Èmí ‘ba l’ẹ́gbẹ̀rún ahọ́n,
Nkò lè ròyìn ná tàn;
Ìfẹ́ Rẹ̀ sí mi pọ̀ jọjọ,
Ago ‘bùkún mi nkún,
Ore-ọ̀fẹ́ tí kì yẹ́,
Àláfíà bí odò,
Lát’ọ́dọ̀ Olùbùkún;
Ẹ fọpẹ́ fun.

**1. Gbọ́! ìró lí òpópó ayé,**
Bí ti ìgbí omi òkun,
Tí nfi agbára rẹ̀ ru s’ókè,
T’ó sì nkọlu èbúté.

Gbọ́! bí ẹṣẹ̀ ọmọ ogun,
Bí wọ́n ti nrìn lọ lí ọ̀nà nà,
Àrẹ́ mú wọn fún ‘sẹ́ àt’ìrìn àjò,
Àti ìjà kíkorò;
Ṣùgbọ́n wọ́n gbàgbọ́, wọ́n tẹjúmọ́,
Ọ̀nà ná t’áwọn mímọ́ ti nrìn,
Bí wọ́n ti nlọ ní ‘gbàgbọ́,
Wọ́n ndágbà n’nú Ọlọ́run Alàyè.

2. Wọ́n ntẹ̀síwájú pẹ̀lú ‘gbàgbọ́,
Tí ẹ̀kọ́kẹ̀kọ́ kò lè mì;

Wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run,
Lè pèsè f'áìní gbogbo.

3. Dàpọ̀ mọ́ wọn, àyé wà síbẹ̀,
Dúró de 'bùkún Ọlọ́run:
Òun ni 'rètí gbogbo àgbáyé,
Lati ṣiṣẹ ododo.

## **Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo ìgbìmọ̀ àti ìmọ̀ràn búburú, tó n gbógun ti ìfarahàn ògo mi yóò kùnà gẹ́gẹ́ bí ó ti ri fún Àhítófẹ́lì, ní orúkọ Jésù.
2. Ìfòróróyàn láti ṣiṣẹ́ akin fún ìran mi, ayé mi ṣí sílẹ̀ fún ọ, wọlé, ní orúkọ Jésù.
3. Agbárakágbara tí wọ́n yàn láti mú ààbò àtòkèwá kúrò lọ́dọ̀ mi àti ìdílé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹnubodè àánú, ojúrere àti ìfarahàn ògo, ṣí fún mi nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Rẹ, Olúwa, jẹ́ kí ayé mi bẹ̀rẹ̀ siní ṣàfihàn ògo Rẹ, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìdíwọ́ àti ìdènà sí ìtẹ̀síwájú mi tó farasin, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
7. Ojúrere àti àánú àtòkèwá, farahàn nínú ipò ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti pa ayọ̀ mi run, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo kòtò tí àwọn ìránṣẹ́ ikú gbẹ́ fún ayé mi, gbé ẹni tí ó ni ọ́ mìn, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìpinnu, ìdájọ́ àti gbólóhùn àjọ àjẹ́, tó lòdì sí ògo ayànmọ́ mi, rún wómúwómú, ní orúkọ Jésù.
6. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, yọ́ dánù, gbogbo gbólóhùn tí wọ́n yàn láti fa ayànmọ́ mi lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, tú gbogbo ìpéjọpọ̀ tó lòdì sí ayànmọ́ mi ká, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ</u>

**2 Kọ́ríntì 9:8** Ọlọ́run sì lè mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ ma bísi i fún nyín; kí ẹ̀nyin, tí ó ní ànító ohun gbogbo nígbàgbogbo, lè ma pọ̀ si i ní iṣẹ́ rere gbogbo:

**Jeremíàh 29:11** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò sí nyín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún íbi, láti fún nyin ní ìgbà ìkẹyìn àti ìrètí.

**Fílíppì 4:19** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Rómù 15:13** Njẹ́ kí Ọlọ́run irètí kí ó fi gbogbo ayọ̀ òn àláfíà kun nyín ní gbígbàgbọ́, kí ẹ̀nyin kí ó lè pọ̀ ní irètí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́.

**Orin Dáfídì 103:1-4** Orin Dáfídì. Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, àti gbogbo ohun tí ó wà nínú mi, fi ibùkún fún orúkọ Rẹ̀ mímọ́. Fí ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ̀: Ẹnití ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ, Ẹnití ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé.

## ÌJẸ́WỌ́ ÀTI ÀDÚRÀ SÓRÍ OHUN-ÈLÒ IṢẸ́

Bàbá, mo fi ohun-èlò làálà/iṣẹ́/òwò mi sí ọwọ́ mímọ́ Rẹ. Jẹ́ kí àwọn ohun-èlò wọ̀nyí kún fún ojúrere àtòkèwá, ònfà ìṣèrere, afa-àlàjá-mọ́ra, ìtayọ, agbára láti jẹ́ ẹni tí n winni, kì íṣe atọrọ, ìfàmì-òróró-yàn tó n yí ìtàn padà sí rere, àwọn àlàjá tíkòwọ́pọ̀, àti àgbègbè tó gbòòrò, ní orúkọ Jésù.  Mo ri ohun-èlò làálà/iṣẹ́/òwò mi sínú ẹ̀jẹ̀ Jésù àti iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.

1. Mo fọ́ ègún òṣì nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ẹ̀mí tó n mu ẹ̀jẹ̀ ọrọ̀ mi, mo gbé ọ dè, ní orúkọ Jésù.
3. Mo bá gbogbo ajẹnirun nínú ètò-ìṣúná mi wí, ní orúkọ Jésù.
4. Mo tú agbárakágbára tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìmúnádóko mi ká, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí ọrọ̀ àwọn kefèrí gba ìṣípò-padà sọ́dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, darí mi lọ sọ́dọ̀ àwọn tí yóò bùkún fún mi, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí a gbin ònfà ìṣerere àtòkèwá sínú àwọn ọwọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
8. Èmi yóò dìde ga ju àwọn aláígbàgbọ́ tí ó yímiká lọ, ní orúkọ Jésù.

9. Olúwa, ṣe mí ní àtọ́kasí àpẹẹrẹ rere fún ibùkún àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ìfòròróyàn ìtayọ bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, somípọ̀mọ́ àwọn olùrànlọ́wọ́ àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo àwọn tó kórira ìṣerere mi gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
13. Èmi kòní kú láìṣepé adámimọ̀, ní orúkọ Jésù.
14. Èmi kòní kú láìní ìwúlò àti láìjẹ́pé a kókìkí mi sí rere, ní orúkọ Jésù.
15. Èmi kòní kú láìso èso àti láìní ìmúṣẹ, ní orúkọ Jésù.
16. Èmi kòní ju ọwọ́ sílẹ̀ nítorí mo gbàgbọ́ láti rí ire Olúwa ní ilẹ̀ alàáyè, ní orúkọ Jésù.
17. Afẹ́fẹ́ àṣetì kòní fẹ sí ìhá ọ̀dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
18. Mo gba okun Olúwa láti fo odi kòṣééṣe, ní orúkọ Jésù.
19. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo gba àwọn ìyanu tí yóò ya àwọn ọrẹ́ mi lẹ́nu, tí yóò sì já àwọn ọ̀tá mi láyà, ní orúkọ Jésù.
20. Nípa agbára tó pín Òkun Pupa sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí ọ̀nà mí là, ní orúkọ Jésù.
21. Nípa agbára tó pín Odò Jọ́dánì sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí àlàjá mi tíkòwọ́pọ̀ farahàn, ní orúkọ Jésù.
22. Ọlọ́run Èlíjàh, dìde, kí O sì sọmí di àrà merìrí àdìtú, ní orúkọ Jésù.
23. Nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tíkò ṣe é fọ́, mo wọnú ìpele mi tókàn lọ, ní orúkọ Jésù.
24. Àkokò ẹ̀rín mi tíkòwọ́pọ̀ àti ijó ìṣẹ́gun, farahàn, ní orúkọ Jésù.
25. Olúwa, tún àyíká mi tò láti mú ojúrere bá mi, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tú àwọn àlùmọ́nì mi ká, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.

27. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tẹrí ìgbésókè mi ba, kú, ní orúkọ Jésù.
28. Ọ̀pá ìkà tó n gbógun ti ìtẹ̀síwájú mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.